# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 587 THURSDAY APRIL, 23 1964 (2D)

## Ọdaran Kan Ji Pẹpẹiyẹ Gbe

OKENE :- Oju gba gbagbo enia ti fun ọdọmọdekunrin kan, Suberu Adebirika eni ogun ọdun ti awọn ọlọpa mu wa si kotu Ijọba Ibilẹ Okene fun ẹsun ole jija ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi.

Ọlọpa ti o ba ọdaran na ṣẹjọ ṣe alaye niwaju Ile ẹjọ pe, ninu ọsẹ ti o kọja yi, ni ọdaran na yọkẹlẹkẹlẹ ninu ile wọn ti o si lọ gbe pẹpẹiyẹ ọrẹ rẹ, ọgbẹni James Osakwe gbe.

Ọlọpa na tun ṣe alaye pe, ninu Ile kanna ni ọdaran na jijọ n g b e pẹlu ọgbẹni James Osakwe, nigbati o ss ri wipe, ọgbẹni Osakwe ko si nile' ni o bi lo gbe pẹpẹiye rẹ.

Nigbati ọgbẹni Osakwe de, ti ko si ri pẹpẹiyẹ rẹ, ni o b a bẹrẹsi i w a kakiri gbogbo adugbo, awọn aladugbo ti wọn ri ọdaran na nigbati o gbe pẹpẹiyẹ na ni nwọn s ọ fun Osakwe pe ọ r ẹ lo gbe, nwọn juwe ibiti pẹpẹiyẹ n a wa nigbati o si de ibẹ ti o ri i, ni nwọn ba ko ara wọn wa si Tesan ọlọpa.

Nigbati adajọ bi ọdaran na ohunti o ṣe t i o fi gbe pẹpẹiyẹ ọrẹ r ẹ, ọdaran na gba wipe on jẹbi ni adajọ ba ni ki o lọ fi pọnun mẹwa (£10) tanran si kotu.

## ỌDẸSANYA SỌ PE :

# AWỌN ỌLỌPA FI IPA MU UMỌRẸN RO'JỌ NI TEṢAN

EKO:- Gbogbo ile ẹjọ lo palọlọ ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ Kọkanlelogun oṣu yi nigbati Ọgbẹni Micheal Ọdẹsanya nsọ fun Igbimọ ijoko awọn adajọ marun ti nwọn ngbọ ẹjọ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ pe, pẹlu ipa ati inira ni awọn Ọlọpa fi nginu awọn olujẹjọ lati ma a ro ẹjọ ni asiko ti nwọn fi ngmu wọn ti mọle, pẹlu ifoya ni awọn enia na si fi nsọrọ nigbati awọn Ọlọpa bẹrẹsi halẹ mọ wọn.

Oniwe-irohin wa Eiyin'gboro ti o nlọ si Ile ẹjọ na fi ye wa pe, ẹjọ ala ni ojọ ijẹta yi jẹ fun Ọgbẹni Ọdẹsanya, odidi wakati merin lo fi sọrọ n i w a j u awọn a d a j ọ nigbati ẹjọ na si bẹrẹ, ọpọlọpọ ibere ni awọn adajọ bere lọwọ Ọgbẹni Ọdẹsanya.

Ọkan ninu awọn Agbẹjọro na sọ fun Ejongboro pe, ibere yi ni o ti pọju lati igbati ile ẹjọ na ti bẹrẹ lati ọsẹ keji sẹhin.

Ninu awọn enia mẹtadinlogun ti Ijọba mba ṣẹjọ na, enia mẹia ninu wọn ni Ọgbẹni Ọdẹsanya nṣenu fun ninu wọn, awọn enia na si nwọnyi.

Ọgbẹni Micheal Omishade, G a b b y Shaṣọrẹ, Adeyiga Adesanya, Sylvester_Umọrẹn, U. I. Nwao-



Ọlọla Ade. Ademọla



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

biala ati Samuel Otubanjọ.

AWIJARE

Nigbati Ọgbẹni Ọdẹsanya bẹrẹ ẹjọ awijare rẹ niwaju ijoko, ọkọkan ni o ngmu ẹjọ na, ti o si nṣe alaye bi o ti ṣe jẹ wipe, adajọ ṣi ara rẹ lọna ninu idajọ rẹ.

Ọgbẹni Ọdẹsanya wa ṣe akiyesi ẹjọ ti adajọ Agba Ṣhowẹmimọ da fun ọgbẹni Otubanjọ, o si ka diẹ si etigbọ awọn adajọ na.

O tun ṣe akiyesi ninu ọrọ rẹ pe, adajọ ko nilati ju Otubanjọ si ẹwọn ọdun meji rara, nitoripe ko jẹbi ẹsun meji ti adajọ sọ pe o jẹbi rẹ.

Ọ g b ẹ n i Ọdẹsanya ni adajọ sọ pe, o jẹbi ẹsun pe o ba awọn kan ṣe ipade.

Ekeji ni wipe, o lọ si Ghana lati lọ kọ iṣe ogun lati le gbe ogun ti Obabiorin Gẹẹsi, ki nwọn doju Apapọ Ijọba bole, ki wọn si fi ipa gba akoso Ijọba na, gẹgẹbi ẹri ti o jade lati ẹnu Patrick Dokotri.

Ọgbẹni Ọdẹsanya wa pe akiyesi awọn adajọ na si ẹjọ ti Oloye Ekwejunor-Etchie, ọkan n i n u awọn Olujẹjọ na ti adajọ ti fi silẹ.

Ninu ẹjọ tirẹ ti o ro niwaju a d a j ọ, Ekwejunor-Etchie sọ pe, on ko ba ẹnikeni ṣe i p a d e ni Ibadan nigbati Patrick Dokotri sọ pe on ṣe ipade pọ pẹlu awọn kan.

Ṣugbọn nigbati adajọ nṣe idajọrẹ, o ni on ni igbagbọ si ẹjọ ti Oloye Ekwejunor Etchie ro, niwaju on, o si da Oloye na silẹ pe, ko si ninu ipade nitorina ki o ma a lọ layọ ati alafia.

Ọgbẹni Ọdẹsanya wa sọ fun ile ẹjọ pe, nitori ọrọ ipade yi kanna ti Otubanjọ ko si nibẹ gẹgẹbi Ọgbẹni Dokotri ti wi ni adajọ ṣe ju Otubanjọ si ẹwọn ọdun meji.

O wa rọ ile ẹjọ na pe, ko si otitọ kan lati ẹnu awọn ẹlẹri Ijọba pe Otubanjọ wa ninu ipade na, ko si ẹniti o rojọ fun adajọ Ṣowẹmimọ pe, nitootọ lo wa ninu ipade ti awọn kan ṣe ni Ibadan.

Nigbati mo bẹrẹsi sọrọ mi ni ibẹrẹ iwe yi, mo sọ fun nyin pe, ọpọlọpọ ibeere ni awọn adajọ bi Ọgbẹni Ọdẹsanya ninu ọrọ rẹ.

Nibiyi ni Ọdẹsanya sọrọ de, ki awọn adajọ to ma a bere ọrọ lọdọ rẹ, Bi o ti sọ ọrọ yi tan ni, Ọlọla Louis Mbanefo, Olori awọn adajọ Ipinlẹ Ila Orun Naijiria wa bere lọwọ Ọgbẹni Ọdẹsanya pe.

MBANEFO: "Ipade wo ni o nsọ n i p a rẹ, ṣe eyiti nwọn ṣe ninu oṣu kejila ọdun 1962?"

Ọ D Ẹ S A N Y A: "Bẹni Oluwa mi, ipade kan ṣoṣo ti nwọn ṣe na ni eyiti nwọn ṣe ni ọjọ kejila oṣu kejila ọdun na."

Ọgbẹni Ọdẹsanya sọ pe niwọn igbati adajọ ti le gba ẹri Oloye Etchie gbọ, ti o si da lare, pe ki o ma a lọ layọ ati alafia nitoripe ẹlẹri ododo ni.



Ọgbẹni M. A. Ọdẹsanya

Nigbati adajọ ti le ṣe eleyi, lori ipade yi, ko tun ni ẹtọ kan mọ ni abẹ ofin lati ju Otubanjọ si ẹwọn mọ lori ipade kanna.

Lẹhin adajọ ti ṣe eleyi, ẹnikẹni ni o le ri dajudaju pẹlu mi wipe, adajọ ṣi ara rẹ lọna, ko si si ofin kan

WO OJU EWE KẸFA

# IWE SI OLOTU

## Irohin Imọlẹ Oju Ewe Mejila

Olotu, ẹ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin ti njade lojojumọ lati ba awọn alaṣẹ iwe Irohin Imọlẹ sọrọ to ndun mi ni ọkan. Awọnjẹnia mi ati emi na ni a ma sọ pe o yẹ ki iwe Irohin Imọlẹ to oju ewe mẹjọ si mejila.

Gẹgẹbi ko ti si iwe irohin ni ede Yoruba ti o le ba Irohin Imọle forigbari, bẹ si ni gbogbo wọn ni o ni ewe mẹjọ si mejila, mo ro pe awọn nkan to ba dara fun ọkunrin o yẹ ki o dara fun obinrin pẹlu.

Ko ye mi idi ti iwe na ko fi ju ewe mẹfa lọ, gbogbo enia ni o fẹ ma ka itan aladun nitoripe oju ewe iwe na je mẹfa ni a ki ti gbadun iwe na to rara.

Mo dupẹ lọwọ awọn to nṣiṣẹ ninu ile iṣẹ na, a ngbadun iṣẹ ti ẹ nṣe, Olorun yio ran gbogbo nyin lọwọ lati ọdọ Olotu titi de ọdọ ọm iranṣe to wa ninu ile iṣe na.

Inu mi dun fun aye ti ẹ gba mi o.

Emi ni,
M. A. ONIPEDE,
*Eko.*

## Ẹ Ti Ogunde Silẹ.

INU mi yio dun pupọ bi Olotu bale gba mi ni aye ranpe ninu iwe Irohin Imọle agbọrọdun fun gbogbo ọmọ ile Yoruba lati ba Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Oru sọrọ atata, nitoripe ọna ti nwọn gba da Ogunde ati elere rẹ duro ko dara to rara.

Ọlọrun ma gba onjẹ lẹnu wa o Amin. Ọgbẹni Ogunde ko ni iṣẹ meji ti oju iṣẹ orin lọ, loju temi, onje ni ẹgba ni ẹnu rẹ yi, awọn ẹmi ti o rọ ma nkọ? Awọn Iyawo, Ọmọ ti nkawe, awọn elere ati bẹẹbẹ lọ nkọ? Kini ki nwọn o ma a jẹ?

Gẹgẹbi ẹ ti nwa iṣọkan ilẹ Yoruba, ti o ba jẹpe, ete lasan ki ẹ fi nwi, ki ẹ tete jẹ ki Ọgbẹni Ogunde ati awọn elere rẹ bẹrẹ si ṣe ere wọn, nitoripe ọna ọrun, ọna ọfun ati ọna ọfun ọna ọrun, bi ọna ọfun badi pẹrẹ ọna ọrun nilati la sile ni

Nigbati Yoruba ba nfi iya jẹ Yoruba to bayi ti awọn agbagba ba nworan, boba ya, ẹ wa ma pariwo pe, Ibo nyan nyin jẹ, nigbati ẹnyin alara nyan ara nyin ta ẹnikan ko sọrọ rara?

Emi ni,
J. O. ALAO

Iwo

## Babashọla Nfẹ Atunṣe

Inu mi yio dun pupọ bi Olotu ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe re oloyin momọ ti njade lojojumo lati kesi Ijọba Apapọ ki nwọn ba wa tun Babashọla se ni asiko yi, nitoripe asiko ojo ni awa yi.

Ẹ ni ti o ba rin ọna na ni yio mọ pe, oju ọna na ko dara to rara, paapa lati Babashọla lọ si Ọbẹlẹ gbogbo oju ọna na nri ati jatijati to je pe kodara fun moto rin

Bi awọn ọkọ tabi moto ba kọja nibẹ ni ẹkan, ko ni tun fẹ lọ si ibẹ mọ, nitori oju ọna na le ba moto na jẹ fun awọn koto to wa loju ọna na.

Inu wa ko ba dun bi ẹba le tete ba wa tun awọn oju ọna na ṣe ni asiko, nitoripe bi ilẹ wa bi dara ti awa enia tun rẹ ko ni alafia, ilu wa ko ti dara na ni yi.

Mo dupẹ lọwọ Olotu fun aye ti ẹgba mi ajinde ara yio majẹ amin.

Emi ni,
OLUFUNKẸ KỌLAWỌLE
Suru-lere

## Ẹrukobodo Nkọ

Ẹ dahun, gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin oloyinmomọ lati bere Alagba wa, ọmọ-ọba Adefarakan ti gbogbo aiye mọ apele orukọ rẹ gege bi Ẹrukobodo onige ewura olori ọ le ti wọ ewu ṣegu ti i ma a sọ orişirişi itan sinu iwe Irohin Imọlẹ ti a si ma a ngbadun itan rẹ.

Inu wa yio dun bi alagba wa Ẹrukobodo ba le tun bere lati ma



Ọgbẹni Ẹrukobodo

sọ itan aladun rẹ fun wa ninu iwe Irohin Imọle, ongbe ọrọ itan aladun re ngbe wa jọjọ.

Inu wa yio dun si tun dun bi Olotu ba le fi iwe yi ran si baba wa na ki o si mọ wipe, awa onkawe Irohin Imọle ko le gbagbe baba wa na. Bi o ba si lọ si idalẹ ni, a fẹ ki olotu j ki mọ ibiti Baba iwa na ba wa.

Bi o ba si jẹ wipe olotu ba baba wa na ja ni, a fẹ ki olotu tete lọ tọrọ aforijin lọdọ baba wa na pẹlu idọbalẹ

Mo dupe fun aye ti ẹ gba mi ọkọ ọba ko ni ṣa njin lẹsẹ o

Emi ni
J. A. ADESHILE
Awẹ

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI-

RICHALET

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO

Eleyi yatọ patapata si awọn Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọn mọnọ




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹẹ ti nwọn si nti kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyẹn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni lẹ yi,

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba awọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Iatambulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa Egbogi-Amodi Apo ile ilọ, ẹhin didun tabi baradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa nba ẹjẹ ara rẹ patapata yio si nṣ ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomina pẹlu

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street ( Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji)

FAH! REMEMBER THAT

**The Social Dandies**

*PRESENTS*

**An id-Ul-Kabir Dance**
AT
**FORESTER CENTERY HALL**

22, Ọdunlami Street, Lagos. On Sunday 26th Apri 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn
*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest heats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E., Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing.

**Tickets: 4/- Flat**

Tickets now on sale at 3, Oluşhi Street Lagos 16, Bamgboṣe Street, Irohin Imọlẹ's Office Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Mẹtta.

O ku ọjọ marun loni.

## Ikomọ Ọmọ Disu Miringindin

EKO:- Ẹnu kọ irohin ni inawo ọmọ ọkunrin ti Ọgbẹni Mohammed Mansurudeen Abioye Abọlọrẹ Disu ṣe ni ile rẹ, 11/13 Upper King Street, ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu kẹta ọdun yi.

Ọlọrun ni o fi ọmọ na ṣikẹ Ọgbẹni na ati aya rẹ, Adiatulai Amọpe, ọmọ Lemọmu Agba t i Mọṣalaṣi Jimọ.

Ero pọ bi iyẹpe (iyanrin) ni ibi aṣeyẹ ọjọ na. Hadji Immam ti Mọṣalaṣi Iduntafa ni o si ṣe akanṣe isin isọmọlorukọ. Awọn baba ọmọ na ati awọn ẹbi iya rẹ na wabi-wọsi owo lọjọ na.

## Aṣoju Titun

IBADAN:- Ni i p a de Apapọ ti awọn ọmọ Ile Igbimọ Aṣofin ti Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ṣe ni ọjọ Ajẹ ti iṣe ogunjọ oṣu yi ni awọn Igbimọ na yan awọn Aṣoju titun mẹta kan si Ile Igbimọ ti awọn agba oṣelu ilẹ Naijiria l'Eko.

Awọn aṣoju mẹta yi yio rọpo awọn Aṣoju ile Igbimọ A g b a ti o ti Ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria wa ti awọn ọmọ ile Igbimọ na si ti kuro nigbati Ipinlẹ ti ya kuro lara Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 20 - Feb 18) Ara rẹ yio walẹ lọni iwọ yio le ṣe gbogbo awọn nkan ti o ti nro ọ loju lati ṣe. Iwọ yio ri oju rere nipa owo loni, oni yi dara lati tẹpa mọ ẹkọ rẹ.

PISCES (Feb 19 - March 20) Ọjọ arẹ ni oni yi yio jẹ fun ọ, ṣugbọn mura ki o tunrase lati le ṣe gbogbo nkan to ba yọju si ọ pẹlu iyanju, Gbọ ti ara rẹ loni, ọrọ iwọ pẹlu ọmọbinrin kan yio wọ ara wọn lalẹ oni.

ARIES (Mar 21 - Apl 19) Sagbara rẹ lati pari gbogbo iṣẹ to wa nilẹ, o dara ki o kọwe ranṣẹ si awọn ọrẹ rẹ lokere, maṣe wa mọto loni, nitori ewu wa fun ọ, ma ṣe fọwọ kan ẹrọ.

TAURUS (April 20 - May 20) Gbogbo ẹhun ti o ba dawọle loni, rere ni yio jasi, Iwọ yio ba obinrin kan ṣe faaji loni, ọrọ iwọ pẹlu awọn ẹbi rẹ yio wọ ara wọn.

GEMINI (May 21 - June 21) Bi o ba ti tunra rẹ ṣe, iwọ yio ri ere pupọ jẹ. Maṣe ya enia ni owo, bẹni ki o maṣe ya owo funra rẹ, Maayọ pẹlu awọn ti o nyọ ma ṣe ba ẹbi re kan ja.

CANCER (Jun. 22 - Jly 22) Ṣe iranlọwọ fun enia, ki ire ba le jẹ tirẹ, tọju ara rẹ loni, ki o ba le gba iyi larin ẹgbe,

LEO (Jly 23 - Aug 22) Ohun pupọ ni yio farahan fun ọ lati ṣe, ṣugbọn ko nṣe gbogbo rẹ ni yio yọri si rere iṣẹ ti o nṣe yio ma lọ daradara, awọn ẹbi rẹ yio si gbadun,

VIRGO (Aug 23 - Sept 22) Gbogbo nkan yio ṣoro fun ọ fun igba diẹ yio ma mu ija dani bi o ba mba ẹlomiran sọrọ ṣugbọn orire ti o ni yio jẹki o bori ohun gbogbo

LIBRA (Sept 23 - Oct 23) Ọjọ oni dara fun ọ lati ni ọrẹ pupọ iwọ yio ri nkan iyanu kan nibi iṣẹ na loni, Ṣe pẹlẹpẹlẹ nipa ọrọ owo ki o maṣe na inakuna, obinrin kan yio ba ọ ṣere

SCORPIO(Oct 24–Nov 22) Ara rẹ yio le, iwọ yio si de ibiti o fẹ de gẹgẹbi ọkan rẹ ti nfẹ. Ayọ ati idunu yio bẹ silẹ larin iwọ ati awọn ẹbi rẹ, iwọ yio gbọ ihin lati okere wa

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Nkan ko ni fi bẹ su ọ fun a k o k o diẹ arẹ okan ati irẹwẹsi yio wa fun ọ nigba diẹ, owo yio tẹ ọ lọwọ bi o ba gbajumọ iṣẹ rẹ Kọwe si awọn ọrẹ rẹ lokere

CAPRICORN (Dec 23-Jan 19) Ọjọ oni y i da a, ṣugbọn o yẹ ki o ni suru, nitori ija kan ti yio ṣẹlẹ, o si le jẹ ija iwọ pẹlu awọn ẹbi rẹ, ṣe suru ki ija na maṣe ju bẹ lọ Alẹ oni yio gbadun


BI O BA NI

# Iwe—Titẹ

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ ẸRỌ—ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16. Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN

*OWO PỌKU NI A SI NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Dan wa wo lẹẹkan ṣoṣo ki o si ri iyatọ*


## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ni ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu yi (26/4/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba *16*, Bamgbose Street Eko.

A o si yan awọn Alaṣẹ ẹgbẹ titun, eyi ti gbogbo ipade ti fi ohun sọkan lati yan ninu ipade ti a ṣe gbehin yi. Nitorina maṣe alai ko wa, boya oye na le kan ọ.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki ẹ tete de o.

LATIFU BABALỌLA
Adele Akowe


## Congreve.s Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn obinrin ti o ba ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ẹkọọkan ẹhin-didun, Ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹdudu ara tabi aikotọ ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugba Igba — aiya riru ọmu riro, didun arẹ atinu wa ti oma nfa oyi - oju Ilaogun ara ẹsẹ ara sisọn, ẹfọri abi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo O b i n r i n gẹgẹbi Ajo fun ilera ati orişirişi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni in nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:-

**Ammoniated Quinine Tincture**

Nigba lailai ki awọn Orişirişi rọbirọki egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ aju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji ti a i p e r i nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itoju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ opo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi aju didun tabi ti ọwa-ọfun didun, ati orişirişi omira pẹlu wọn mbẹ ni ṣọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, Palm Church Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

# BARIKA — DE — SALLAH

**Lati Ọwọ S. O. Jaiye, Eko**

O BẸRẸ LATI ANA

Idahun yi ya mi lẹnu pupọ. Nitori Ọlọrun ni ki Anabi Ibrahim fi ọmọ rẹ rubọ fun on lati dan igbagbọ rẹ wo.

Şugbọn bi Ọlọrun ti ri pe Anabi Ibrahim ti fẹ dawọ le ọmọ rẹ lati pa ni Ọlọrun sọ fun pe ki o maşe be! Ọlọrun si sọ fun pe wo agbo to wo lọhun ini lati fi dipo ọmọ na Isaac, Ọmọ Ileri ninu iru ọmọ rẹ ti yo fọ Esu lori

Eyi nipe ẹniti Anabi Isa yo şegun rẹ lehin ọla, oro Ọlọrun kan na to sọ iru enia ti Anabi Isa jẹ ti nwọn ko gba apakan ninu awọn ọ ọ pe ọmọ Ọlọrun ni On şe

Ninu ope ati aimokan wọn ro pe, Ọlọrun ri bi enia fun igbeyawo ati ibimọ mo sọ eyi ninu ẹmi pe eyi ko ri bẹ rara.

Ọlọrun wipe ọmọ ni, ọmọ si ni nitotọ, Eyi to ku di ọwọ Ọlọrun papa. Yiyan ati şişe ki şe ti ẹda a fi ti Oluwa wa.

BABA IGBAGBỌ

Ninu gbogbo ọrọ Ọlọrun ohun ti Oluwa fẹ ki ẹda şe pẹlu aşẹ ni O ranşẹ si enia lati şe fun ibọwọ fun On ati fun anfani.

Nigbati aiye wa ni juju ti eto isin Ọlọrun ko yẹ ọmọ enia irubọ wa. Irubọ na ni lati ma sun ohun ẹbọ si Ọlọrun bakanna o h u n ọgbin wa fun irubọ si Ọlọrun,

Baba nla Ibrahim ti anpe ni Nahor ati baba Anabi Ibrahim (Abraham) ti a npe ni Tẹrn Ere ati Orisa ni nwọn ma nsin.

Itan sọ fun ni pe botilẹ jẹ pe Orişa ni awọn idile Ibrahim nsin tabi ma nsin şugbọn on nikan ni ẹni na to kọ gba pe Ọlọrun kan lo wa.

Nigbati Ọlọrun wa pe ki O jade kuro ni ile rẹ lọ si ibi ti ko mọ ri, ọrọ Ọlọrun sọ pe o jade lọ şugbọn on ko mọ ibiti o nre. Nitoti idi awọn wọnyi ni afi pe Abraham nla baba Igbagbọ ati ọrẹ Ọlọrun.

Aşa ti awọn ara mi ninu Ẹsin sọ di tiyantiyan loni pe ki a ma pa ẹran ko si



Ọgbẹni S. O. JAIYE

ninu iwe aşẹ Ọlọrun bẹ rara. Mo si fẹ fi ye awọn to npa ẹran Ileya loni pe ki şe aşẹ Ọlọrun rara fun wọn lati pa ẹran.

Ti o ba jẹ wipe nwọn ko aşa Anabi ni mo ro pe o yẹ ki nwọn tẹ pẹpẹ ki nwọn si dana sabẹ pẹpẹ yi ki a fi ẹran na şe irubọ lori pẹpẹ gẹgẹbi Anabi Ibrahim ti şe fun ọmọ Ileri rẹ Isaac ti ki şe Ishmael gẹgẹ bi nwọn ti ro,

Nitotọ Ishmael jẹ ọmọ Hagar Ẹrubinrin Sarah ti şe ọmọ ilẹ Misira (Egypt) ẹniti o bi fun Ibrahim.

ONIYẸYẸ

Ọpọ ọrọ lori amulumala awọn itan Ishmael ti a ngbọ lori ero aşọrọ magbesi ko bọsi rara. Ẹdẹ ni ọrọ Ọlọrun. Ko si alọ ti a le pa lori ọrọ na ki Otitọ ma yanju kedere.

Dipo ti awọn olugbọ ẹni yo ma yin ẹni, ẹrin ni nwọn yo ma fi ẹni rin fun iwa aimọkan ati ailoye lori ọrọ Ọlọrun.

IGBỌRAN

Nitorina mo fi taratara ki gbogbo ẹnyin ọmọ iya mi ninu ẹsin Ọlọrun ku iyedun Mo si ba nyin yọ fun Iforibalẹ sinsin Ọlọrun Ọga Ogo.

Nipari ọrọ Ikini yi Ọlọrun wipe on ko ni mu didun si ọrẹ ẹbọ sisun ati ọra agbo lọ.

Ọlọrun ni ifeti silẹ si ohun Oluwa ko ha san ju ọra agbo lọ?

Ẹjẹ ki a ma sin Ọlọrun ni ona to pe ki a fi isin atọwọdọwọ silẹ. Ki Ọlọrun na ti a nsin ko da wa lare nikẹhin ọjọ aiye wa gbogbo.

Ẹ ku Iyedun, a şe yi şe ẹmi i.


AFRICAN SPECIAL

* Full tropicalisation and underbody protection plates
* Strong and comfortable suspension.
* Outstanding road holding.
* Modern workshops and spare parts stores, manned by Factory Trained Staff.
* HIGH RESALE VALUE.

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE METTA, IBADAN KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT HARCOURT & ABA

